# A SỌ ASỌTẸLẸ IGBA IPỌNJU NLA

**Isaiah 24:1-23; 26:19-21; 34:1-8**

**ẸKỌ 351 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Wá, enia mi, wọ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi ẹnipe ni iṣẹ́ju kan, titi ibinu na fi rekọja" (Isaiah 26:20).**

**I Idajọ Ọlọrun lori Ilẹ**

1 Oluwa yoo bẹ ayé wò ati awọn olugbe inu rẹ, Isaiah 24:1, 3, 4; 26:21; 34:1-3; 13:11; Matteu 24:21, 22; 2 Tẹssalonika 1:7-9

2 Idajọ Ọlọrun yoo wà lai ṣègbè, Isaiah 24:2; 34:2-5; Johannu 12:48; Romu 2:8, 9; Kolosse 3:25; 1 Peteru 1:17

3 A fi ilẹ gegun nitori ẹ̀ṣẹ awọn eniyan, Isaiah 24:5-12; Gẹnẹsisi 3:17; Jeremiah 44:22

4 Awọn eniyan diẹ ni a o dá si, wọn o si yin Ọlọrun logo, ṣugbọn awọn eniyan buburu ki yoo le sá àsálà, Isaiah 24:16-18, 21, 22; 34:6-8; Owe 11:21; 19:5; Amosi 9:1-4; Matteu 23:33; Romu 2:3; Heberu 2:3

5 Ilẹ yoo ta gbọn-ọn gbọn-ọn gẹgẹ bi ọmuti eniyan, Isaiah 24:19, 20; 2:19; 13:13; Ifihan 11:19

**II Aabo fun awọn Olododo**

1 A o ji awọn okú mimọ dide, ati awọn olododo ti o wà laaye ni a o gbà si awọsanma ṣaaju igbà ipọnju naa, Isaiah 26:19, 20; 1 Kọrinti 15:19-22, 51-54; 1 Tẹssalonika 4:13-17; Ifihan 20:4

2 Oluwa awọn ọmọ-ogun yoo jọba ni Jerusalẹmu ni opin ìgbà ipọnju naa, Isaiah 24:23; 2:1-3; Sẹkariah 14:9, 16, 17; Ifihan 11:15; 19:11-16

## ALAYE

"A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de …nigbana ni ipọnju nla yio wà, irú eyi ti kò si lati igba ibẹrẹ ọjọ iwa di isisiyi, bẹ̃kọ irú rẹ̀ ki yio si si" (Matteu 24:14, 21). A ti waasu Ihinrere Ijọba ni gbogbo orilẹ-ède ayé, ọ̀pọlọpọ eniyan ni o ti kọ̀ ọ́; nitori naa Ipọnju Nla ni yoo si tẹle e. Bi a ba wo inu ayé loni, a o ri i gbangba bi imisi buburu ti ẹ̀ṣẹ, ati ifara hàn iṣẹ Eṣu ti n bo gbogbo ẹda ayé mọlẹ. O dabi ẹni pe bi anfaani ẹkọ ati imọ ti n ga si i, bẹẹni ọkàn awọn eniyan n fà kuro ninu ododo ati iwa-bi-Ọlọrun tó. Bibeli wi bayii pe: "Awọn enia buburu, ati awọn ẹlẹtàn yio mã gbilẹ siwaju si i, nwọn o mã tàn-ni-jẹ, a o si mã tàn wọn jẹ" (2 Timoteu 3:13).

### Awọn Idajọ ti n Bọ̀

Oluwa kilọ ninu Ọrọ Rẹ̀ pe ẹlẹṣẹ ati ẹ̀ṣẹ ki yoo lọ lai jiya. Asọtẹlẹ Isaiah sọ fun ni bi ijiya yii yoo ti tànká tó li ọjọ ibinu Oluwa: "Kiyesi i, OLUWA sọ aiye di ofo, o si sọ ọ di ahoro, o si yi i po, o si tú awọn olugbé inu rẹ̀ ka" (Isaiah 24:1). Kò si ẹni ti o wà laaye ti yoo bọ́ kuro ninu idajọ Ọlọrun ni ọjọ naa. Gbogbo eniyan ni yoo jiya ẹ̀ṣẹ ti wọn ti dá. Awọn eniyan naa yoo jiya, ati awọn wolii èké ti n kọ́ wọn, ti o si n fi ọkàn wọn balẹ sori asán; awọn oluwa ninu ayé ti wọn le fi owo wọn ra ohun rere ti ayé ati ayọ̀ yoo jiya pẹlu awọn ọmọ-ọdọ ti n ṣe iranṣẹ fun wọn; iranṣẹ-binrin ati oluwa rẹ̀, olura ati oluta, atọrọ ati awinni – gbogbo wọn ni yoo bá ibinu ati idajọ Ọlọrun pade nitori ti wọn kọ eto igbala Ọlọrun ti i ṣe fun awọn olugbé ayé.

### Didà Majẹmu

Laaarin awọn wolii nla ti igba Majẹmu Laelae, Isaiah tayọ gẹgẹ bi wolii alasọtẹlẹ nipa irapada; ṣugbọn o sọ ohun pupọ pẹlu nipa idajọ ti n bọ̀ lori awọn aṣayan ilu ati lori ayé lapapọ. O dabi ẹni pe gbogbo ayé ni a dari ọrọ idajọ ti o wà ninu ori kẹrinlelogun Iwe Isaiah si, a si ka awọn idi ti idajọ fi n bọ̀: "wọn ti rú ofin, wọn pa ilàna dà, wọn dà majẹmu ayeraye."

Gbogbo ẹ̀ṣẹ ti eniyan n dá ni inu Ọlọrun kò dùn si, ṣugbọn eyi ti o dabi ẹni pe o buru ju ninu ẹ̀ṣẹ ti eniyan n dá ni kikọ Kristi. Lati igba ti eniyan ti kọkọ dá ẹ̀ṣẹ si Ọlọrun ni O ti ṣeleri pe Oun yoo rán

Olurapada ti yoo ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ eniyan. Gbogbo eniyan ni majẹmu ayeraye yii wà fun. Lati ayebaye ni Ọlọrun ti n sọ ileri yii di ọ̀tun, ti otitọ naa si n sunmọ-tosi titi o fi di akoko igba ti Ọlọrun rán Ọmọ Rẹ̀ Jesu Kristi si ayé lati jiya ati lati kú ikú irubọ lori Agbelebu, pe nipa Ẹjẹ Jesu ki a le gba gbogbo eniyan là. "Ọlọrun ----nisisiyi o paṣẹ fun gbogbo enia nibi gbogbo lati ronupiwada: Niwọnbi o ti da ọjọ kan, ninu eyiti yio ṣe idajọ aiye li ododo, nipasẹ ọkunrin na ti o ti yàn; nigbati o ti fi ohun idaniloju fun gbogbo enia, niti o ji i dide kuro ninu okú" (Iṣe Awọn Apọsteli 17:30, 31).

Ohun idaniloju kan ṣoṣo ti o le yọ ni kuro ninu ẹ̀ru ati ijiya Ipọnju Nla ni igbọran si gbogbo ilana majẹmu ayeraye – tabi ni kukuru, gba Jesu Kristi gbọ́, jẹwọ gbogbo ẹ̀ṣẹ ti o ti dá, ki o si gbọran si Ọlọrun, ki o si fẹ Ẹ pẹlu gbogbo ọkàn, iye, inu, ati agbára rẹ. O ṣe ni laanu pe, gbogbo ayé lapapọ kò fẹ́ tẹriba fun, bẹẹni wọn kò si fẹ́ gba gbogbo ipese majẹmu naa. Nitori ti wọn kọ lati gba ifẹ otitọ ti a ba fi gbà wọ́n là, awọn ti o pọju ninu awọn eniyan ti o wà ninu ayé ni yoo parun.

**Ipọnju Nla**

Ẹ̀ṣẹ ti ṣiṣẹ ibi lọpọlọpọ ni igbesi-ayé ọmọ-eniyan lati ọdunmọdun; ṣugbọn akoko Ipọnju Nla yoo jẹ́ igba idajọ ti kò si irú rẹ̀ ri. Akoko iyọnu ti wà ṣaaju ri, ṣugbọn kò si eyi ti yoo dabi igba ipọnju ti a sọrọ nipa rẹ̀ yii ninu Ọrọ Ọlọrun ni gbogbo itan agbaye. Ipọnju Nla naa yoo wà fun ọdun meje. Nigba ti ipọnju naa ba n lọ si opin ni a o rán idajọ gbigbona sori gbogbo orilẹ-ède ayé, Ju ati Keferi bakan naa, fun gbogbo aiwa-bi-Ọlọrun wọn ati kikọ Ihinrere ati iṣẹ ti Kristi rán si wọn. Yoo jẹ igba ibanujẹ kikoro, irora ati inira, lara ati lọkan fun gbogbo ẹda ti o wa laaye. Ẹṣẹ ati iwa buburu yoo dé ogogoro ninu idajọ gbigbona nla yii.

"Ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká," ni Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa, bi akoko ifunrugbin ti daju bẹẹ gẹgẹ ni akoko ikore yoo dé pẹlu.

Ọrọ Ọlọrun fi ye ni pe ki i ṣe ohun kekere ni lati yi pada kuro lẹyin Oluwa ati lati ká abayọri sí ẹ̀ṣẹ. Awọn ẹlomiran a maa fẹ ṣe awawi pe wọn jẹ ope si Ọlọrun ati Ofin Rẹ, ṣugbọn Ọlọrun wi pe "wọn mọ̃mọ ṣe aifẹ̃mọ" (2 Peteru 3:5). Ko si awawi kan fun ẹ̀ṣẹ ti yoo duro ni akoko idajọ yii, nitori ti Ọlọrun ti pese ohun gbogbo silẹ lati mu ẹ̀ṣẹ kuro ninu ọkàn ọmọ eniyan. Idajọ ki i ṣe ohun ti o wuni-lori, ṣugbọn o jẹ apakan pataki ninu Ọrọ Ọlọrun paapaa nitori awọn nnkan wọnni ti o n daya fo ayé.

**Aṣodi-si-Kristi**

"Egbé ni fun aiye ati fun okun! nitori Ẹ̀ṣu sọkalẹ tọ̀ nyin wá ni ibinu nla, nitori o mọ̀ pe igba kukuru ṣá li on ni" (Ifihan 12:12). Eṣu ti jà ni Ọrun ṣugbọn kò le bori, nitori naa yoo sa gbogbo ipa rẹ̀ ninu ayé lati bi eto Ọlọrun wó. Ni gẹrẹ ti a ba ti gba Ijọ Ọlọrun -- awọn Onigbagbọ aṣẹgun ni kikun – soke kuro ninu ayé, eṣu yoo gbá ogun jọ, yoo si gbé eto buburu rẹ̀ kalẹ lati jọba lori ilẹ ayé.

Jesu wá bi Ọrọ Ọlọrun ti o gbe ara wọ̀, Ọmọ Ọlọrun ti a fi hàn ninu ara; bakan naa ni Aṣodi-si-Kristi yoo wá gẹgẹ bi eṣu ti o gbé ara wọ̀, oun paapaa ni o duro fun eṣu. Gbogbo iwà ati iṣe Aṣodi-si-Kristi yii ni a tò fun ni lẹsẹẹsẹ ninu Bibeli. Alailofin ni, ẹni ti kò bẹru Ofin Ọlọrun tabi ti eniyan. Eyi hàn gbangba ni ode-oni nitori ayé ailofin ni a n gbé lọjọ oni. Ohun ti o ba irẹpọ ti o wà laaarin awọn orilẹ-ède jẹ ni awọn ọjọ wọnyi ni ṣiṣe ainaani ofin, tabi adehùn, tabi ọrọ ileri ti o wà laaarin wọn; gbogbo rẹ̀ ni wọn ti ṣá ti. Kikọ Ofin Ọlọrun silẹ patapata wà laaarin awọn orilẹ-ède miiran pẹlu. Awọn wọnyi jẹ diẹ ninu awọn ami ti n fi hàn pe Aṣodi-si-Kristi kò ni pẹ de mọ́.

Yoo jẹ aninilara, iwa buburu ati ikà rẹ yoo ju ti ẹnikẹni lọ. Nipa ipọnni ni yoo fi de ipo giga rẹ; ṣugbọn gẹrẹ ti o ba ti de àye rẹ̀ tán, pẹlu ipa ni yoo fi mu gbogbo ayé lati tẹri ba fun un. Nigba ti Danięli n sọ nipa rẹ, o wi bayii pe oun yoo "ma bu ọla fun ọlọrun awọn ilu olodi," nida keji ẹwẹ yoo ṣe àpọnlé ogun jija.

Ni ọjọ oni nigba ti gbogbo ayé n fi gbogbo agbara wọn kó nnkan ogun jọ ti wọn si n sagbàrà yi ara wọn ká, eto ogun ti di ohun ikinni ninu èto ọ̀pọlọpọ orilẹ-ède. Ọpọ orilẹ-ède ni o gbẹkẹle agbára ogun-jija lati mú ifẹ inu wọn ṣẹ; fifi ipa mú orilẹ-ède tẹri ba jẹ́ ohun ti o wọ́pọ̀ laaarin awọn orilẹ-ede ologun wọnyii. Wọn kò tun ni igbẹkẹle ninu ọgbọn-ẹwẹ ti iṣelu tabi ti ilaja mọ́. Wọn kò tun gbiyanju ati pade ara wọn lapapọ ni ọna ti o tọ ki wọn si yanju gbogbo iṣoro wọn lọna ti o tọ́: ṣugbọn wọn n pinnu lati bori nipa lilo ipá – iru iwa Aṣodi-si-Kristi gan an ni eyi.

**Ami Ẹranko Naa**

Igbesi-ayé Kristi ta gbogbo igbesi-ayé ẹnikẹni yọ gẹgẹ bi aṣoju ododo Ọlọrun fun gbogbo ayé. Nida keji ẹwẹ, Aṣodi-si-Kristi yoo wá gẹgẹ bi aṣoju iwa buburu. Ẹranko buburu ẹlẹru nì. A fi i wé ẹranko ninu Ọrọ Ọlọrun; gbogbo awọn eniyan ti o ba kù silẹ ninu ayé ni akoko ijọba Aṣodi-si-Kristi ni a o fi agbára mu lati gba àmì ẹranko buburu naa si iwaju tabi ni ọwọ otun wọn tabi ki wọn sọ ẹmi wọn nù. Ofin Aṣodi-si-Kristi naa yoo le to bẹẹ gẹ ki "ẹnikẹni má le rà tabi ki o tà, bikoṣe ẹniti o bá ni ami orukọ ẹranko na, tabi iye orukọ rẹ̀" (Ifihan 13:17). A fi awọn ti o ba gba ami ẹranko naa gegun kikoro: "Bi ẹnikẹni ba nforibalẹ fun ẹranko nì, ati aworan rẹ̀, ti o si gbà àmi si iwaju rẹ tabi si ọwọ́-rẹ̀, On pẹlu yio mu ninu ọti-waini ibinu Ọlọrun, ti a tú jade li aini àbula sinu ago irunu rẹ̀; a o si fi iná ati sulfuru da a loró niwaju awọn angẹli mimọ́, ati niwaju Ọdọ-agutan: Ẹ̃fin oró wọn si nlọ soke titi lailai, nwọn kò si ni isimi li ọsán ati li oru, awọn ti nforibalẹ fun ẹranko na ati fun aworan rẹ̀, ati ẹnikẹni ti o ba si gbà àmi orukọ rẹ̀" (Ifihan 14:9-11).

**Ọna Abayọ**

Bi a ti n kà nipa ijọba Aṣodi-si-Kristi ninu Ọrọ Ọlọrun, ati awọn ohun buburu wọnni ti yoo ṣẹlẹ lakoko Ipọnju Nla, a le dupẹ pe Ọlọrun ti lana kan silẹ ti a fi le sá asala ni akoko yii. Jesu Kristi n pada bọ̀ si ayé lati wá mu awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ ti n duro de E --awọn ọmọ Rẹ̀ wọnni ti wọn ti mura silẹ lati pade Rẹ̀. "Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti On ti ariwo, pẹlu ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde: nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa ó si ma wà titi lai lọdọ Oluwa" (1 Tẹssalonika 4:16, 17).

Ọlọrun dá Noa si nigba ti a fi omi pa ayé rẹ̀, Ọlọrun dá Lọti si nigba ti a pa Sodomu ati Gomorra run. O da Israẹli si nigba ti angẹli apanirun la Egipti kọja. Bẹẹ gẹgẹ ni O ti pese ọ̀na atila silẹ fun awọn eniyan Rẹ̀ kuro ninu Ipọnju naa. "Wá, enia mi, wọ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi ẹni pe ni iṣẹ́ju kan, titi ibinu na fi rekọja. Nitorina, kiye si i, Oluwa ti ipò rẹ̀ jade lati bẹ̀ aiṣedede ẹniti ngbe ori ilẹ wo lori ilẹ; ilẹ pẹlu yio fi ẹ̀jẹ rẹ̀ hàn, ki yio si bò okú rẹ̀ mọ" (Isaiah 26:20, 21). O jẹ́ ọranyàn fun ọmọ-eniyan lati jẹ́ ipe Ihinrere lonii nitori ọjọ-de-ọjọ ni n fi àmi ti o daju hàn pe dide Kristi sunmọ tosi.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi pinnu pe idajọ yoo wá sori ayé?

2 Awọn wo ninu olugbe ayé ni Ọlọrun yoo dá lẹjọ?

3 Ki ni "majẹmu aiyeraiye" jasi fun ayé lọjọ oni?

4 Bawo ni awọn eniyan ṣe da "majẹmu aiyeraiye" naa?

5 Nigba wo ni Ipọnju Nla naa yoo dé sori ilẹ ayé?

6 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn ti o gba ami ẹranko buburu nì lakoko Ipọnju Nla?

7 Ṣe apejuwe diẹ ninu awọn ohun buburu ti yoo ṣẹlẹ lori ilẹ ayé lakoko Ipọnju Nla.

8 Ọna wo ni a fi le bọ́ kuro ninu Ipọnju Nla naa?